60

# PETERU KINNI

**(A.D. 60)**

ORI 1.

**Ìkíni.**

PETERU, Aposteli Jesu Kristi, si awọn àyànfẹ ti nṣe àtìpó ti wọn túká kiri si Pọntu, Galatia, Kappadokia, Asia, ati Bitinia. (2 Pet 2:1; A.A. 2:5,9.)

2. Gẹgẹ bi ìmọ̀tẹ́lẹ̀ Ọlọrun Baba, nipa isọdimímọ Ẹmí, sí igbọran ati ìbùwọ́n ẹ̀jẹ̀ Jesu Kristi: Ki oore-ọfẹ ati alaafia maa bi si fun yin. (2 Tess 2:13; Heb 10:22; 2 Pet 1:2.)

**Kristi ti a ji dide.**

3. Olùbùkún ni Ọlọrun ati Baba Jesu Kristi Oluwa wa, ẹni ti o tún wa bí, gẹgẹ bi ọpọlọpọ aanu rẹ̀, sinu ìrètí ààyè nipa ajinde Jesu Kristi kuro ninu òkú. (2 Kor 1:3; Jms 1:18; 1 Kor 15:20.)

4. Sinu ogún àìdíbàjẹ́, ati àìlábàwọ́n, ati eyi ti ki i ṣá, ti a ti fi pamọ́ ni ọ̀run dè yin. (Kol 3:24.)

5. Ẹ̀yin ti a npamọ́ nipa agbara Ọlọrun nipa igbagbọ si ìgbàlà, ti a mura lati fihan ni ìgbà ikẹhin. (Jhn 10:28.)

6. Ẹ yọ̀ ninu eyi pupọ, bi o tilẹ jẹ pe nisinsinyìí fun ìgbà diẹ, niwọnbi o ti yẹ, a ti fi ọpọlọpọ ìdánwò bà yín ninu jẹ́: (Rom 5:2; 1 Pet 5:10; Jms 1:2.)

7. Ki idanwo igbagbọ yin, ti o ni iye lori ju wura ti i ṣègbé lọ bi o tilẹ̀ jẹ́ pe iná ni a fi ndan an wo, lè yọrísí ìyìn ati ògo ati ọla ni ìgbà ifarahàn Jesu Kristi. (Jms 1:3; Psm 66:10; Rom 2:7.)

8. Ẹni ti ẹyin fẹ lairi, ẹni ti ẹyin gbàgbọ́, bi o tilẹ jẹ́ pe ẹ kò ri i nisinsinyìí ẹ̀yín si nyọ ayọ̀ ti a kò lè fi ẹnù sọ, ti o si kun fun ogo: (1 Jhn 4:20; Jhn 20:29.)

9. Ẹ̀yín si ngba òpin igbagbọ yin, àní igbala ọkàn yin; (Rom 6:22.)

**Awọn woli jẹri si ìyà Kristi ati Ogo ti yoo tẹ̀le e.**

10. Ìgbàlà tí awọn woli wadi, ti wọn si wa jinlẹ̀, awọn ti wọn sọ asọtẹlẹ ti oore-ọ̀fẹ́ ti nbọ fun yin: (Matt 13:17; 26:24.)

11. Wọn nwadi ìgbà wo tabi irú saa wo ni Ẹmí Kristi tí ó wà ninu wọn ntọka sí, nigba ti o jẹri ìyà Kristi ati ogo ti yoo tẹ̀le e. (2 Pet 1:21; Isa 53.)

12. Awọn ẹni ti a fihàn fún, pe ki i ṣe fun awọn tikarawọn, bikoṣe fun awa ni wọn ṣe iranṣẹ ohun wọnyìí fún, ti a ròhìn fun yin nisinsinyìí, lati ọdọ awọn ti o ti nwaasu ihinrere fun yin pẹlu Ẹmí mimọ ti a rán wa lati ọ̀run; ohun ti awọn angẹli nfẹ lati wò. (Dan 9:24; Ef 3:10.)

**Ìpèníjà si ìgbé-ayé mímọ́.**

13. Nitori naa ẹ di ọkàn yin ni àmùrè, ẹ maa wà ni airekọja, ki ẹ si ni ireti kíkún si oore-ọfẹ, eyi ti a nmu bọ̀ fun yin ni ìgbà ifarahan Jesu Kristi. (Ef 6:14; 1 Tess 5:6.)

14. Bi awọn ọmọ ti nṣegbọ́ràn, laida ara yin pọ̀ mọ́ ifẹkufẹ àìmọ̀ yín ti àtijọ, (Rom 12:2; Ef 4:18.)

15. Ṣugbọn gẹgẹ bi Ẹni ti o pè yin ti jẹ mímọ́; bẹẹ ni ki ẹyin naa jẹ mímọ́ ninu ìwà yin gbogbo. (2 Kor 7:1.)

16. Nitori a ti kọ ọ pe, "Ẹ jẹ́ mímọ́: nitori ti emi jẹ mímọ́!" (Lef 11:44.)

17. Bi ẹyin ba si nkepe Baba, ẹni ti nṣe idajọ gẹgẹ bi iṣẹ́ olúkúlùkù laiṣe ojusaju eniyan, ẹ maa lo ìgbà àtìpó yin ni ìbẹ̀rù: (Deut 10:17; Heb 12:28.)

18. Niwọnbi ẹyin ti mọ̀ pe, a kò fi ohun idibajẹ rà yin pada, bi fadaka tabi wura kuro ninu ìwà asán yín, ti ẹyin ti jogun lati ọ̀dọ̀ awọn baba yin, (1 Kor 6:20; Eks 20:18.)

19. Bikoṣe ẹ̀jẹ̀ iyebiye, bíi ti ọ̀dọ́-agutan ti kò lábùkù, ti kò sì lábàwọ́n, ani ẹ̀jẹ̀ Kristi. (Eks 12:5.)

20. Ẹni ti a ti mọ̀ tẹ́lẹ̀ nitootọ ṣaaju ipilẹṣẹ ayé, ṣugbọn ti a fihan ni ìgbà ikẹhin wọnyìí nitori yin, (Ef 1:4; Heb 9:26.)

21. Ani ẹyin tí o tipasẹ rẹ̀ gba Ọlọrun gbọ́, ẹni ti o jí i dide kuro ninu òkú, ti o si fi ògo fun un; ki igbagbọ ati ireti yin lè wà lọdọ Ọlọrun.

22. Niwọnbi ẹyin ti wẹ ọkàn yin mọ́ nipa igbọran yin si otitọ *(nipasẹ̀ Ẹmí) si ìfẹ́ ará ti kò ni ẹ̀tàn, ẹ fẹ́ ọmọnikeji yin gidigidi lati ọkàn wá. (Jms 4:8; Heb 13:1; Heb 4:12.)

23. Bi a ti tun yin bí, ki i ṣe lati inu ìdíbàjẹ́ wá, bikoṣe èyí ti ki i díbàjẹ́ nipa ọ̀rọ̀ Ọlọrun ti nbẹ láàyè ti o si duro. (Jhn 3:3; Heb 4:12.)

24. Nitori pé, "Gbogbo ẹran ara dabi koriko, ati gbogbo ogo rẹ̀ bi ìtànná koriko. Koriko á maa gbẹ ìtànná a sì maa rẹ̀ dànù. (Isa 40: 6:9.)

25. Ṣugbọn ọ̀rọ̀ Oluwa duro titi lae", Ọ̀rọ̀ naa yìí sì ni ihinrere ti a waasu fun yin. (Jhn 1:1.)

## ORI 2.

NITORI naa ẹ fi àránkan gbogbo lélẹ̀ ni apakan, ati ẹ̀tàn gbogbo, ati àgàbàgebè, ati ilara, ati sisọ ọ̀rọ̀ buburu gbogbo. (Ef 4:22; Jms 1:21; 4:11.)

2. Bi ọmọ-ọwọ́ titun, ki ẹ maa fẹ́ wàrà ti Ẹmi, eyi ti ko lẹ́tàn, ki ẹ̀yín lè maa tipasẹ rẹ̀ dàgbà si igbala. (Mk 10:15; 1 Kor 3:2.)

3. Bi ẹyin ba ti tọ́ ọ wo pe, oloore ni Oluwa: (Heb 6:5; Tit 3:4.)

**Kristi okuta igunlé wa.**

4. Ẹni ti ẹ̀yín ntọ̀ bọ, bi okuta ààyè, ti a ti ọwọ́ eniyan kọ̀ silẹ nitootọ, ṣugbọn lọdọ Ọlọrun àṣàyàn, iyebiye. (ẹsẹ 7.)

5. Ẹyin pẹlu, bi okuta ààyè, ni a kọ́ ni ile ẹmi, alufa mimọ, lati maa rú ẹbọ ẹ̀mí, ti i ṣe itẹwọgba lọdọ Ọlọrun nipa Jesu Kristi. (Heb 13:15; Filp 4:18.)

6. Nitori o nbẹ ninu iwe-mimọ pe, "Kiyesi i, mo fi pataki okuta igunle àṣàyàn, iyebiye, lélẹ̀ ni Sioni: ẹni ti o ba si gba a gbọ́ ojú ki yoo ti i." (Isa 28:16; Ef 2:20.)

7. Fun ẹ̀yin ti e gbà á gbọ́, o ṣe iyebiye; ṣugbọn fun awọn ti kò gbà á gbọ́, "Okuta ti awọn ọmọ̀lé kọ̀ silẹ̀, oun ni o di pataki igunlé," ( Psm 118:22.)

8. Ati pẹlu, "okuta idigbolu, ati apata-ìkọ̀sẹ̀," Nitori wọn kọsẹ̀ nipa ṣiṣe àìgbọ́ran si ọ̀rọ̀ naa sinu èyí ti a gbe yàn wọn si pẹlu. (Isa 8:14; 1 Kor 1:23; Rom 9:22; Matt 21:42.)

9. Ṣugbọn ẹ̀yin ni ìran ti a yàn Olu Alufa, Orílẹ-èdè mimọ eniyan ọ̀tọ̀ ki ẹyin le fi ọla-nla ẹni tí ó pè yin jade kuro ninu òkùnkùn sinu ìmọ́lẹ̀ ìyanu rẹ̀ hàn: (Deut 10:15; A.A. 26:18.)

10. Ẹyin ti ki i ṣe eniyan nigbakan rí, ṣugbọn nisinsinyìí, ẹyin ti di eniyan Ọlọrun, ẹyin ti kò ri aanu gbà rí, ṣugbọn nisinsinyìí, ẹ ti ri aanu gbà.

**Onigbagbọ ati Alaigbagbọ.**

11. Olufẹ, mo bẹ̀ yín, bi alejo ati èrò, lati fà sẹ́hìn kuro ninu ifẹkufẹ ara, ti nba ọkàn jagun; (Rom 12:1; Psm 39:12; Gal 5:16; Jms 4:1.)

12. Ki ìwà yin laarin awọn Keferi dára; pé, bi wọn ti nsọrọ yin bi oluṣe buburu, nipa iṣẹ́ rere yín, ti wọn o maa kiyesi, ki wọn lè maa yin Ọlọrun logo lọjọ ìbẹ̀wò. (Filp 2:15; 1 Pet 3:16; Matt 5:16.)

**Ìhùwàsí onigbagbọ pẹlu awọn ijọba.**

13. Ẹ maa tẹriba fun gbogbo ìlànà eniyan nitori ti Oluwa: ìbáà ṣe fun ọba, bí fun olori. (Rom 13:1.)

14. Tabi fun awọn baalẹ, bi fun awọn ti a rán lati ọdọ rẹ̀ fun ìgbẹ̀san lara awọn ti nṣe buburu, ati fun ìyìn awọn ti nṣe rere. (Rom 13:3,4.)

15. Bẹẹ ṣa ni ifẹ Ọlọrun, pe ni rere ṣiṣe, ki ẹ lè dá òpè awọn wèrè eniyan lẹ́kun: (1 Pet 3:17; Tit 2:8.)

16. Bi ominira, láìsì lo ominira yin fun ohun bíbo arankan yin mọlẹ, ṣugbọn bi ẹrú Ọlọrun. (Gal 5: 1; 1 Kor 7:22.)

(22) *(Awọn Bibeli atijọ miran fi eyi kún tiwọn.)

17. Ẹ bọ̀wọ̀ fun gbogbo eniyan, ẹ fẹ awọn ará. Ẹ bẹru Ọlọrun, ẹ bọwọ fun ọba. (Rom 12:10; Heb 13:1.)

**Ọmọ-ọ̀dọ̀ ati ọ̀gá rẹ̀.**

18. Ẹyin ọmọ-ọdọ, ẹ maa tẹriba fun awọn ọ̀gá yin pẹlu ibẹru gbogbo, ki i ṣe fun awọn ẹni rere ati oniwa tútù nikan, ṣugbọn fun awọn ònrorò pẹlu. (Ef 6:5.)

19. Nitori pe èyí ni ìtẹ̀wọ́gbà, bi eniyan ba fi orí ti ibanujẹ, ti o si njiya laitọ, nitori ọkàn rere si Ọlọrun. (Rom 13:5.)

20. Nitori ogo kínni ó jẹ́, nigba ti ẹ ba ṣẹ̀ ti a si lu yin, bi ẹ ba fi suuru gba a? Ṣugbọn nigba ti ẹyin ba nṣe rere ti ẹ si njìyà, bi ẹ ba fi suuru gbaa, èyí ni itẹwọgba lọdọ Ọlọrun. (1 Pet 3:17.)

**Kristi apẹẹrẹ nla wa.**

21. Nitori inu èyí ni a pè yin sí: nitori Kristi pẹlu jìyà fun yin, o fi apẹẹrẹ silẹ fun yin, ki ẹyin lè maa tọ ipasẹ̀ rẹ̀: (Isa 16:24; A.A. 14:22.)

22. Ẹni nigba ti kò dẹ́ṣẹ̀, bẹẹ ni a kò sì rí àrékérekè lẹnu rẹ̀: (Isa 53:9.)

23. Ẹni, nigba ti a kẹ́gàn rẹ̀, ti ko si padà kẹ́gàn; nigba ti o jìyà ti kò si halẹ̀; ṣugbọn o fi ọ̀ràn rè le ẹni ti nṣe idajọ ododo lọ́wọ́: (Isa 53:7; Heb 12:3; Luk 23:46.)

24. Ẹni ti O tikararẹ fi ara rẹ̀ ru ẹ̀ṣẹ̀ wa lori igi, pé ki awa lè di òkú si ẹ̀ṣẹ̀ ki a si di ààyè si ododo: nipa ìnà ẹni ti a mu yin larada. (Heb 9:28; Rom 6:2; Isa 53:5.)

25. Nitori ti ẹyin nṣáko lọ bi agutan, ṣugbọn nisinsinyìí ẹyin ti pada si ọ̀dọ̀ Olùṣọ́-agutan ati Bisọbu ọkàn yín.

## ORI 3.

**Ìwà laarin Ọkọ ati aya.**

BẸẸ gẹgẹ, ẹyin aya, ẹ maa tẹriba fun awọn ọkọ yin; pé, bi ẹnikẹni ba tilẹ̀ nṣe aigbọran si ọ̀rọ̀ naa, ki a lè jèrè wọn lai sọ̀rọ̀ nipa ìwà awọn aya wọn. (Ef 5:22; 1 Kor 7:16.)

2. Nigba ti wọn ba nwo ìwà rere pẹlu ẹ̀rù yín:

3. Ki ọ̀ṣọ́ yin maṣe jẹ ọ̀ṣọ̀ òde, ti irun dídì, ati wura lílò, tabi ti aṣọ wíwọ̀; (1 Tim 2:9; Isa 3:18–23.)

4. Ṣugbọn ki ó jẹ́ ti ẹni ti o farasin ni ọkàn, ninu ọ̀ṣọ́ aidibajẹ ti Ẹmí ìrẹ̀lẹ̀ ati ẹmi tútù, eyi ti i ṣe iyebiye niwaju Ọlọrun. (Rom 7:22.)

5. Nitori bayìí ni awọn obinrin mímọ́ igbaani pẹlu, ti wọn gbẹkẹle Ọlọrun, fi ṣe ara wọn lọ́ṣọ̀ọ́, wọn a maa tẹriba fun awọn ọkọ tiwọn. (1 Tim 5:5.)

6. Gẹgẹ bi Sara ti gbọ ti Abrahamu, ti o npe e ni oluwa. Ọmọbinrin ẹni ti ẹyin jẹ́, bi ẹyin ba nṣe rere, ti ohunkohun ko si dẹ́rùbà yin (Gen 18:12.)

7. Bẹ gẹgẹ ẹyin ọkọ, ẹ maa fi òye ba awọn aya yin gbé, ẹ maa fi ọlá fun aya, bi ohun èlò ti kò lagbara, ati pẹlu bi ajumọ-jogun oore-ọfẹ ìyè; ki adura yin má ba à ni ìdènà. (Ef 5:25; 1 Tess 4:41; Matt 5:23.)

**Àyẹ̀wò nipa ìwà onigbagbọ.**

8. Lakotan, ki gbogbo yin jẹ́ oninu kan, ẹ maa bá ara yin kẹ́dùn ẹ ní ìfẹ́ ará, ẹ maa ṣe ìyọ́nú, ẹ ni ẹ̀mí ìrẹ̀lẹ̀. (Filp 2:3; 1 Pet 5:5.)

9. Ẹ maṣe fi buburu san buburu, tabi fi èébú san èébú: ṣugbọn kàkà bẹẹ, ẹ maa sure; nitori èyí ni a pè yín sí, ki ẹyin lè jogun ìbùkún. (Rom 12:17; Heb 6:14.)

10. Nitori, "Ẹni ti yoo bá fẹ ìyè, ti yoo sì rí ọjọ́ rere, ki o pa ahọ́n rẹ̀ mọ́ kuro ninu ibi, ati ètè rẹ̀ mọ́ kuro ninu sisọ ọ̀rọ̀ ẹ̀tàn: (Psm 34:12–16; Jms 1:26; 1 Pet 2:1,22.)

11. Ki o yà kuro ninu ibi, ki o si maa ṣe rere; ki o maa wá alaafia, ki o si maa lepa rẹ̀.

12. Nitori ojú Oluwa nbẹ lara awọn olododo, etí rẹ̀ sì ṣí sí ẹ̀bẹ̀ wọn: ṣugbọn ojú Oluwa dojújàkọ awọn ti nṣe buburu."

**Awọn onigbagbọ pẹlu inunibini.**

13. Tani yoo si ṣe yin ni ibi, bi ẹyin bá jẹ́ onitara si ohun rere? (Owe 16:7.)

14. Ṣugbọn bi ẹyin ba jìyà nitori ododo, alaafia ni: ẹ má ṣe bẹ̀rù wọn,

ki ẹ ma si ṣe kọminú; (1 Pet 2:19; 8:12,13.)
15. Ṣugbọn ẹ bọ̀wọ̀ fun Kristi bi Oluwa ni ọkàn yín: ki ẹ si mura tán nigba gbogbo lati dá olukuluku lohun ti nbeere ìrètí ti o nbẹ ninu yin, ṣugbọn pẹlu ọkàn tútù ati ìbẹ̀rù. (Kol 4:6; 1 Pet 1:3; 1:17.)
16. Ki ẹ maa ni ẹ̀rí-ọkàn rere bi wọn ti nsọrọ yín ni ibi, ki ojú lè ti àwọn ti nkẹgan ìwà rere yin ninu Kristi. (Heb 13:18; 1 Pet 2:12,15.)
17. Nitori ó sàn, bi o ba jẹ ifẹ Ọlọrun, ki ẹ jìyà fun ṣiṣe rère jù fun ṣiṣe buburu lọ (1 Pet 2:20,15.)
18. Nitori ti Kristi pẹlu jìyà lẹẹkan nitori ẹ̀ṣẹ̀ wa, olootọ fun awọn alaiṣootọ, ki ó lè mu wa dé ọ̀dọ̀ Ọlọrun, ẹni ti a pa ninu ara, ṣugbọn ti a sọ di ààyè ninu ẹmí: (1 Pet 2:21; 2 Kor 13:4; Ef 3:12; 1 Pet 4:1,6.)
19. Ninu èyí ti o lọ pẹlu ti o si waasu fun awọn ẹ̀mí ninu túbú: (1 Pet 4:6.)
20. Awọn ti o ṣe alaigbọran nigbakan, nigba ti sùúrù Ọlọrun duro pẹ ni saa kan ni ọjọ́ Noa, nigba ti wọn fi kan ọkọ̀ ninu èyí ti a gba awọn diẹ là nipa omi, eyi ni ẹni mẹjọ. (Gen 6:3,5; Heb 11:7; Gen 8:18.)
21. Apẹẹrẹ èyí ti ngba yin la nisinsinyìí pẹlu, ani baptismu, ki i ṣe wíwẹ̀ èérí ti ara nù, bikoṣe idahun ẹ̀rí ọkàn rere si Ọlọrun, nipa ajinde Jesu Kristi. (Tit 3:5; Heb 9:14; 1 Pet 1:3; Rom 6:4,5.)
22. Ẹni ti o lọ si ọrun, ti o si nbẹ lọ́wọ́ ọ̀tún Ọlọrun: pẹlu awọn angẹli, awọn aláṣẹ, ati awọn alagbara ni itẹriba labẹ rẹ̀. (Rom 8:34,38.)

ORI 4.

**Ipenija si iṣẹ́.**

NJẸ bi Kristi ti jìyà fun wa nipa ti ara, irú inu kannaa ni ki ẹyin fi hámọ́ra; nitori ẹni ti o ba ti jìyà nipa ti ara, o ti bọ́ lọwọ ẹ̀ṣẹ̀; (1 Pet 3:18; Gal 5:24.)
2. Ki ẹyin má ṣe fi ìgbà ayé yin iyoku wà ninu ara mọ́ si ifẹkufẹ eniyan bikoṣe si ifẹ Ọlọrun. (Gal 2:20; Rom 6:11.)
3. Nitori ìgbà ti o ti kọja ti tó fun ṣiṣe ifẹ awọn Keferi, rinrin ninu ìwà wọbia, ifẹkufẹ, ọtí amupara, irede òru. kíkó ẹgbẹ́ ọmuti, ati ìbọ̀rìṣà ti i ṣe ohun ìríra. (Ef 4:17.)
4. Eyi ti o yà wọ́n lẹnu pe ẹyin kò ba wọn sure sinu irú aṣejù ìwà wọbia wọn, ti wọn si nsọ̀rọ̀ yin ni buburu. (1 Pet 3:16.)
5. Awọn ẹni ti yoo jíhìn fun ẹni ti o ti mura lati ṣe idajọ ààyè ati òkú. (A.A. 10:42; 2 Tim 4:1.)
6. Nitori eyi ni a sá ṣe waasu ihinrere fun awọn òkú, kia lè ṣe idajọ wọn gẹgẹ bi eniyan nipa ti ara, ṣugbọn ki wọn lè wà láàyè si Ọlọrun nipa ti Ẹmí. (1 Pet 3:19.)
7. Ṣugbọn opin ohun gbogbo kù si dẹ̀dẹ̀; nitori naa ki ẹyin wa ni airekọja, ki ẹ si maa ṣọra ninu adura. (Rom 13:11; 1 Pet 1:13.)
8. Ju gbogbo rẹ̀ lọ, ẹ ní ifẹ ti o gbóná laarin ara yin: nitori ifẹ ni nbo ọpọlọpọ ẹ̀ṣẹ̀ mọ́lẹ̀. (Heb 13:1; 1 Kor 13:7.)
9. Ẹ maa ṣe ara yin ni alejo laisi ìkùnsínú. (Heb 13:2; 2 Kor 9:7.)
10. Bi olukuluku ti ri ẹ̀bùn gbà, bẹẹ ni ki ẹ maa ṣe ìpín funni rẹ̀ laarin ara yin, bi ìríjú rere ti oniruuru oore-ọfẹ Ọlọrun. (Rom 12:6,7; 1 Kor 4:1.)
11. Bi ẹnikẹni ba nsọ̀rọ̀, ki o maa sọ bi ọ̀rọ̀ Ọlọrun, bi ẹnikẹni ba nṣe iṣẹ́-iranṣẹ, ki o ṣe e bí agbara ti Ọlọrun fifun un, ki a lè maa yin Ọlọrun logo ni ohun gbogbo nipa Jesu Kristi, ẹni ti ogo ati Ijọba wà fun lae ati laelae. (Amin.) (Ef 6:10; 5:20; 1 Tim 6:16.)

**Ìpèníjà si iduro ṣinṣin.**

12. Olufẹ, ẹ má ṣe ka idanwo gbígbóná ti nbẹ laarin yin lati dán yín wò bi ẹnipe ohun àjèjì ni o dé bá yin: (1 Pet 1:6,7.)
13. Ṣugbọn niwọnbi ẹyin ti jẹ alabapin ìyà Kristi, ẹ maa yọ̀, ki ẹyin lè yọ̀ ayọ̀ pupọ nigba ti a ba fi ogo rẹ̀ hàn. (Filp 3:10; Rom 8:17.)

14. Bi a ba gàn yin nitori orukọ Kristi, ẹni ìbùkún ni yín: nitori Ẹ̀mí Ogo ati ti Ọlọrun bà lé yín *(ni ọdọ tiwọn, wọn nsọrọ rẹ ni ibi, ṣugbọn ni ọdọ tiyin a yìn ín logo.) (Matt 5:11.)
15. Ṣugbọn ẹ má jẹ ki ẹnikẹni ninu yin jìyà bi apaniyan, tabi bi olè, tabi bi oluṣe-buburu, tabi bi ẹni ti ntojubọ ọ̀ràn ẹlomiran. (1 Tess 4:11.)
16. Ṣugbọn bí ó ba jìyà bi Kristiani ki ojú maṣe ti i; ṣugbọn ki o kúkú yin Ọlọrun logo ni orukọ yìí. (A.A. 5:41.)
17. Nitori ti ìgbà naa de, ti idajọ yoo bẹ̀rẹ̀ lati ile Ọlọrun wá: bi o ba si tètè ti ọdọ wa bẹ̀rẹ̀, igbẹhin awọn ti kò gba ihinrere Ọlọrun yo ha ti rí? (Jer 25:29; Mal 3:5.)
18. Bi o ba ṣe pé agbara kákà ni a fi gba olododo là, nibo ni alai-wa-bi-Ọlọrun ati ẹlẹ́ṣẹ̀ yoo gbe yọju sí? (Owe 11:31; Luk 23:31.)
19. Nitori naa ẹ jẹ ki awọn ti njiya gẹgẹ bi ìfẹ́ Ọlọrun ni ṣiṣe rere, fi ọkàn wọn le Ẹlẹda olootọ́ lọ́wọ́. (2 Tim 1:12.)

ORI 5.

**Ipenija si dídúro ninu igbagbọ.**

AWỌN alagba ti nbẹ laarin yin ni mo gbànímọ̀ràn, emi ẹni ti nṣe alagba bi ẹ̀yin, ati ẹlẹri ìyà Kristi, ati alábápín ninu ogo ti a o fihan: (Luk 24:48; 1 Pet 1:5,7; Ifh 1:9.)
2. Ẹ maa tọju agbo Ọlọrun ti nbẹ laarin yin, ẹ maa bojuto o, ki i ṣe àfi-páṣe, bikọṣe tifẹtifẹ; kó má sì jẹ́ fun èrè ijẹkújẹ, bikòṣe pẹ́lú iyè-inú ti o mura tán. (Jhn 21:16; 1 Kor 9:17; 1 Tim 3:3,8; Tit 1:7.)
3. Bẹẹ ni ki i ṣe bi ẹni ti nlo agbara lori ijọ, ṣugbọn ki ẹ ṣe ara yin ni apẹẹrẹ fun agbo. (Eks 34:4; Filp 3: 17.)
4. Nigba ti olori Oluṣọ-agutan bá sì fi ara hàn, ẹyin o gba adé ògo ti ki i ṣá. (Heb 13:20; 2 Tim 4:8.)
5. Bẹẹ pẹlu, ẹyin ọ̀dọ́, ẹ tẹriba fun awọn alàgbà. Àní, gbogbo yin ẹ maa tẹriba fun ara yín, ki ẹ fi ìrẹ̀lẹ̀ wọ ara yin ni aṣọ: nitori "Ọlọrun kọ ojú ìjà si awọn agberaga, ṣugbọn o nfi oore-ọfẹ fun awọn onírẹ̀lẹ̀." (Jms 4:6; Isa 57:15.)
6. Nitori naa ẹ rẹ ara yin silẹ labẹ ọwọ́ agbara Ọlọrun, ki oun le gbe yin ga lákokò. (Jms 4:10.)
7. Ẹ maa ko gbogbo aniyan yin le e; nitori ti oun nṣe itọju yin. (Psm 37:5; Matt 6:25; Heb 13:5.)
8. Ẹ maa wà ni airekọja, ẹ maa ṣọra; nitori Èṣù ọ̀tá yin, bi kinniun ti nke ramúramù, o nrin kaakiri, o nwa ẹni ti yoo pajẹ. (Luk 21:34; Job 1:7.)
9. Ẹ kọ oju ìjà sii pẹlu ìduro ṣinṣin ninu igbagbọ, bi ẹyin ti mọ̀ pe ìyà kan-naa ni awọn ara yin ti nbẹ ninu ayé njẹ. (Jms 4:7; Kol 2:5; A.A. 14:22.)
10. Ọlọrun oore-ọfẹ gbogbo, ti o ti pè yín sinu ogo rẹ̀ ti ko nipẹkun ninu Kristi Jesu, nigba ti ẹyin bá ti jìyà diẹ, Oun tikararẹ̀, yoo si ṣe yin ni àṣepé, yoo fi ẹsẹ̀ yin múlẹ̀, yoo fun yin lágbá-ra, yoo fi ìdí yin kalẹ. (Heb 13:21; 2 Tess 2:17.)
11. Tirẹ̀ ni ogo ati agbara titi lae. (Amin.)

**Ọ̀rọ̀ ipari ati oore-ọfẹ.**

12. Nitori Silfanu, arakunrin wa olootọ gẹgẹ bi mo ti kà á si, ni mo kọwe kukuru si yin, ti mo ngba yin niyanju, ti mo si njẹri pé, eyi ni otitọ oore-ọfẹ Ọlọrun: ẹ duro ṣinṣin ninu rẹ̀. (2 Kor 1:19; Heb 13:22.)
13. Ìjọ ti nbẹ ni Babiloni, ti a yan, pẹlu ki yin, Bẹẹ si ni Marku ọmọ mi pẹlu. (A.A. 12:12.)
14. Ẹ fi ifẹnukonu ìfẹ́ ki ara, yin. (Amin.) (Rom 16:16.)

---

(14) *(Awọn Bibeli atijọ miran fi èyí kun tiwọn.)